# EJO ALABI AJ'OMOGBE BERE NI KOTU EKO




STANDARD NEW KING
SIZE 4D SIZE 5D.
See you pay the correct price.



ELETI ỌFẸ
A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO



TO CLEAR
Gents Suede Court Shoe
Brown, Black & Grey
Before 30/- Now 29/6
Obtainable at:-
A. B. AKINYẸMI
10A Moloney Bridge
LAGOS.


VOL. No. VIII 481. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, AUGUST, 18, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)

## Ejo Aj'omogbe bere Ni Kotu

**EKO**— Ẹjọ Lamidi Alabi, ọkunrin kan ara Ilọrin to lọ ji awọn ọmọde kekeke mẹta gbe bẹrẹ ninu kotu Eko.

Ẹniti o kọkọ rojọ ni ọmọbinrin wundia kan ti a npe ni Roda Asaba; ọmọ ilẹ Ibo ni. Ọmọ na sọ wipe, on ndana ninu kiṣini lọwọ ni on ri ajọmọgbe na ti o nfi egbogi dudu kan pa awọn ọmọ na loju.

Nigbati on ri bayi, on kepe Iya Alaro ki o tete jade wa wo nkan ti on ri yi. Ọkunrin kan nle tiro fun awọn ọmọ kan pẹlu ipa. Iya Alaro sọ pe nigbati on de ibẹ nitotọ, on ri tiro loju awọn ọmọ na.

Falila Adukẹ tun jẹri wipe, lọna apapa ni on ngbe, ṣugbọn on wa ṣe nkan ni Ita-Faji, ni igbẹ ba bẹrẹ si gbọn on. Bi on ti nyagbẹ lọwọ ni on gbọ ti ọmọ kekere kan nsọ wipe ma le tiro fun mi.

Adukẹ sọ wipe bi on ti jade ni on lọ yọju wo ibiti on ti ngbọ ọrọ yẹn, on si ri awọn ọmọ kekeke mẹta ti nwọn duro lẹgbẹ apoti ofifo kan.

Jarinatu Ajọkẹ, Iya Alaro ti Roda pe yọ'ju lara ọgba, o si ri ọdaran na pẹlu awọn ọmọ.

Jarinatu sọ wipe nigbati on y'ọju on ri awọn ọmọ mẹtẹta ati ọdaran na ti o nle tiro fun Asani, ọmọ na nke, on si jade lọ ba ọdaran na ati awọn ọmọ lati mọ ohun to nṣe fun wọn.

Jarinatu wipe nigbati on de ibẹ, on ba aṣọ funfun kan ti atẹ silẹ pẹlu ẹtu funfun ati nkan bi ogun (egbogi) lori aṣọ na o ni ẹru ba on, ni on ba k'igbe, ti on fi pe Wolewole kan ti o nkọja ni asiko na.

Aderibigbe Oluwo, Wolewle tun jẹri wipe nigbati on gbọ igbe Jarinatu ti o pe on, ni on sunmọ, on si ri ọdaran ati awọn ọmọ ati aṣọ fun-fun pẹlu ogun ati ẹtu gẹgẹbi Jarinatu ti wi. Nigbati ọrọ ri bayi, on fi ẹrọ gbohungbohun (Telephone) pe ọlọpa.

Moses Oyebọde, ọlọpa to wa jẹri sọ wipe awọn gburo ni Ṣọbu ọlọpa ni nwọn yan on lati lọ si Ita Faji. Nigbati on de'be, on ri ọdaran na ti ọpọlọpọ enia yika l'arin won ati awọn ọmọde meta ti nwọn fihan on wipe awọn ọmọ na ni ọdaran ko s'nu apoti.

Fabilatu Adukẹ ti o ngbe Apapa Road, ni Ebute Metta sọ wipe on wa ninu Ile iyagbẹ, on ngbọ igbe awọn ọmọde nitosi Ile iyagbẹ na. Nigbati on jade on lọ si ibẹ lati ri nkan ti o ṣe ọmọ na, on si ri Ganiyu ọmọ ẹgbọn on, Musibawu ati Asani pẹlu ọdaran yi ati apoti nla kan, o sọ wipe on ri igi kan lọwọ ọdaran na ti nwọn ni ofi le Tiro dudu s'oju Asani, on sare lọ sọ fun ẹgbọn on nile.

Enia mẹwa lo jẹri, Morinatu, Ajikẹ, Amusa Lawal baba Musibawu, Adisa Adeakọbi, baba Asani ati Jacob Agalum ọlọpa - inu ni awọn to jẹri ki Adajọ to fi ẹjọ na si ọjọ kẹtadinlogun oṣu Sept, 1956.

Nigbati nwọn bẹrẹ ẹjọ na Adajọ tọkasi awọn ọmọ mẹtẹta o si bere lọdọ Agbẹjọro ijọba wipe ṣe ao fi awọn ọmọ wọnyi ṣe afihan Kotu ni?

Agbẹjọro dahun wipe nda o, mobẹrẹ foji o, mo fẹ ki awọn ẹlẹri fi wọn han ni o.

Gbagbo Kotu bu s'ẹrin.


## THE NATIONAL BANK
### Of Nigeria Limited.

Ile ifi Owo pamọsi yi
Nfi ọna owo han ẹni
Bi o ba fẹ jẹ oniṣowo pataki ao
ran ọ lọwọ nipa wipe ao tọ ọ
si Ọna ti o dara, ao la oju rẹ
si Ọna owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun nṣe iranlọwọ fun
gbogbo ọja ilẹ wa ti nta si agbaiye.

**ILE IṢẸ WA NI EKO :—**
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

**AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—**

The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.

The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.


## ỌLỌLA GOMINA GBOGBO-GBO



Sir James Robertson

Gomina Agba yio de silẹ yi ni ọjọ Monday ti o mbọ yi. O ti lọ ba isinmi lọ silu re lati kan bi oṣu to koja.



Ra Ti Ni
Ile Egbogi
— ISE —
Olodumare
Okebola,
Ibadan.
116, Great
Bridge St.
LAGOS

## FA IJI, K' RU BA'JI

( ati ọwọ ẸSỌ IKOYI.)

Lasiko kan ni Ado Ekiti, ọba kan jẹ nilu na ti a npe ni Ajamgbilẹ. Ọba na jẹ onisuru, ko mbinu, ọpọlọpọ arufin ni o nfi ori ji, ko nṣe ọba ti o gbona rara. Nipa bayi ọpọlọpọ awọn enia lo ri ọba na fin, awọn ijoye ilu na papaa ri ọba na fin arfin ti awọn ijoye ilu nwọnyi lo pọ ju.

Awọn meji wa larin awọn ijoye ilu na ti a npe ni ijoye Aro ati Ọdọfin. Arifin ti awọn meji nwọnyi lo papọrekọja ala. Bi ọba ba gunwa, Aro yio ṣi ade kuro lori ọba, yio gbe ade na de ori, Ọdọfin yio si ma fi ọwọ gba ọba lori, awọn ara ilu ti o duro nworan yio bẹrẹ si ho ge-e-e, nwọn o ma pa atẹwọ, sibẹ eyi ko wipe ki ọba na binu.

Lọjọ kan, Orunmila ṣ'awo lọ si Ado-Ekiti, o wọ sile ọba. lọjọ keji, o difa fun ọba, o si bẹrẹ si ki odu ifa na bayi:-

Bi a ko ba pa iji han iji
Ẹ ru ko mba iji
A difa fun Alado Ekiti
A ni ki o rubọ igiripa obukọ kan
Ki abuku ti nwọn fi nkan a yi le dinku.
Ọba gbọ, o ru, Irẹtẹwo.

Lẹhin ti ọba na rubọ tan, Orunmila ni ki o lọ mu ida rẹ wa o ṣe ifa si ara re, o mu fun ọba pada, o wi fun pe, bi Aro bade ti Ọdọfin si joko, ki ọba wọle, ki o mura gẹgẹbi jagun-jagun ki o fi ida na bẹ Aro lori, ki o siju lu Ọdọfin laiya, ẹru rẹ yio ba wọn, nwọn ko si ni yaju si ọba mọ.

Li ọjọ kejọ gbogbo enia ti peju sinu afin ọba, ọba na si gunwa, bi Aro ti de lo fi ọwọ gba ọba l'ejika, o ku si ẹrin o si gbe ade kuro lori ọba, o fi de ori ara rẹ. Ọba binu dide, o wọ ile, o wọ ṣapa-ṣapa, o wẹ ṣopo-ṣopo, o mura bi ologun, fusa ti o yọ, nṣe lo bẹ Aro lori, o si julu Ọdọfin laiya. Igbọ l'obinrin nfẹ ewe, gbogbo awọn enia ti o fi oju ri nkan na ati ti ko ri salọ, nwọn tilẹ sa jade kuro ni ilu. Nigbati o ṣe ni nwọn wa ronu kan Orunmila, nwọn ni ki o gba wọn.

Orunmila ni ki nwọn lọ mu onjẹ wa fun Ọba wọn, olukuluku lọ eyiti o mu iṣu, agbado, eree, ati eso igi, nwọn ko gbogbo rẹ wa sọdọ ọba wipe, asingba ọdun ti a ko wa fun ọba niyi, ki ọba ye, ki o dakun dabọ. Nigbati nwọn ko silẹ tan Ọba tun fa ida rẹ yọ, gbogbo enia tun rọ giri lọ ba Orunmila, ki o tun gba wọn.

O wi fun wọn pe, ki nwọn lọ p'ẹran fun ọba gbogbo wọn ko sinu igbo, wọn pa orisirisi ẹran wa fun ọba. Nigbayi ni nwọn to ri oju ọba nilẹ. Latigba na wa, ẹnikan ko jẹ fi ọrọ ọba Ado ṣere mọ. Lati igbana ni ọrọ odu-Ifa na ti di Owe ti awọn enia ma npa bayi pe; Bi ako ba pa iji han iji, ẹru ko ni ba iji.

## Egypt Nko Oko Ogun Jo

PORT SAID. Latigba ti Gẹsi ati Egypt ti nfa ilọgbọn mọ ara wọn lọwọ, ti ẹnikan nṣana mọ ẹnikeji, a koiti gbọ wipe ẹnikan ṣigun si ẹnikeji ṣugbọn a gbọ wipe awọn Gesi paṣẹ wipe ki awọn Sọja ma bẹrẹ si ko aṣọ ogun wọ, ki awọn ọkọ ogun wọn si ma dari lọ si eti okun ilẹ Egypt.

Iwọnyi ni awọn ara ilẹ Egypt ri, ti ẹru ba wọn, awọn rọ lọ ba aṣoju ilẹ Rọṣia to mbẹ nilẹ Egypt wipe, ki o maṣe jafara lati ranṣẹ silẹ wọn, ki o maṣe jafara lati ranṣẹ silẹ wọn ki nwọn ko awọn ọkọ ogun wa silẹ Egypt.

IBERE TIWA NIYI

Tabi awọn ara Egypt fẹ fi ọwọ ara wọn fa ogun nla ni ndan? gẹgẹbi iwe Apejuwe Aiye ti kọ wa, ọna mẹta ni Rọṣia ni lati rin ki nwọn to ko ọkọ ogun wọn de Egypt. 1. Nwọn o rin okun North Atlantik titi wa de Gibralter, Gẹsi ko si ni jẹki nwọn kọja nibẹ nitoripe awọn ni Alaṣẹ ibẹ. 2. Nwọn le gba ọna okun dudu, ṣugbọn bi nwọn ba de Constantinople, awọn Tatambulu ko ni jẹki nwọn kọja. 3. Nwọn tun le gba ọna okun Pasifik lati wa wọ okun pupa ṣugbọn Gẹsi lo ni ebute Aden ko si ni jẹki nwọn kọja.

## Awon Ero Meka

KANO. Iye awọn enia to lọ ṣe Hadji lọhun lati ilẹ enia dudu ni apa Iwọ Orun ilẹ Afrika jẹ 1,774 ti nwọn ba ọkọ ofurufu fo lọ lati ilu Kano si Mẹka.

Ninu iye awọn enia yi enia mejidilọgbọn ni ẹmi rẹ rasu lọhun. Ọlọrun ko mu ẹsẹ awọn yoku dele ni alafia. Amin.

Alhaji to ṣẹṣẹ de
Ba a da amuda
Owe lawani rẹ kere
Ba a da amuda

## A ha le ma so iru eyi loro bi?

Lọjọ kan ti Alufa Kokewu Kobere nṣe wasi ni ojude Ọrẹkofẹrọ nilu Eko Alufa na bẹrẹ si sọ iru iṣẹ ti Ọlọrun nṣe oju ati ẹsẹ awọn Alufa lope sibẹ.

Bi alufa na ti nsọrọ lọ, bẹni ọkunrin kan dide duro o wipe Alufa jọwọ da ọrọ ti o nsọ duro nibẹ, eyiti o sọ wipe Ọlọrun ṣe

(Wo yoku loju ewe keje)

## Ebi ki wo'nu k'oro miran wo.

Eb npa Ọkọnrin Hausa kan ko ri ohun ti yio jẹ ẹni o taju kan, o ri Obinrin ti o nta ẹkọ nkọja lọ, o pe e.

K... Mekafa Mekafa Obinrin ... ṣugbọn ... pe tẹ ẹ, o s... o lọ.

Inu ... na nitori ti ẹlẹkọ ... ko dahun, o sa tẹra mọ npe Mekafa Mekafa nigbati o ri wipe ẹlẹkọ na fẹ ṣẹ kọrọ, o ni Ka... Eleko nigbayi ni ẹlẹkọ to mọ pe on ni nwọn pe.

Ọrọ yi na lo di owe bayi wipe, ebi ko pa Gambari, o npe Mekafa, nigbati ebi ja a jẹ o pe Eleko.

Nigbati ẹlẹkọ de ti o sọkalẹ Gambari wa bẹrẹ si ba wijọ pe, "kiniṣe ti iwọ ko gbu oro" Ẹlẹkọ si dahun wipe bẹni, nigbati ebi koiti pa Gambari lo npe Mekafa nitoripe Mekafa ko gbe gambari ṣugbọn nigbati ebi doju rẹ, ni Gambari pe Eleko.



Sir Anthony Eden
British Premier.

Aworan Alakoso Igbimọ ilu Oyinbo Gẹsi (Prime Minister) ti o ṣi ipade apero ti ilu mẹrinlelogun l'ori Itọ odo ti a npe ni Zuez Canal ti nwọn bẹrẹ nilu nla London lọjọ Alamisi, 15th August, 1956.

Ki Oluwa tọ wọn si ọna alafia ni adura tiwa.



## Grammar Yoruba

1. Eyi ni ijade nipa Grammar Yoruba ti o jade ninu iwe irohin wa ti ọjọ 28th oṣu July 1956.
1. Ojo – The name of a person
2. Ojo – The rain.
3. Ojo – The Coward.
(2) 1. Ogun – The God of Iron.
2. Ogun – The Medicine
3. Ogun – The War
4. Ogun – Inheritance
5. Ogun – Twenty

Iwọnyi ni orukọ awọn to ja ọrọ na:-

No. 1. Z. O. Famakinwa,
YẸKINNI ANJỌRIN,
ISAAC THOMPSON,
SAULA A. BALOGUN
J. O. Adedokun,
S. T. Abayọ, R. Alaka, S. M. Ilọri,
P. Adegun, Z. O. Adelẹyẹ.

No. 2. Z. O. Adelẹyẹ, nikan lo yanri kedere ti ko si aṣiṣe. Diẹ ninu aṣiṣe niwọnyi. Long – o/gun, Sweat - Oogun. A ko mọ ede ilu ti Ọgbẹni S. O. Lanloye lo, bi Ekiti ni tabi Ijẹsha.

## Ode Pade Ode, Ologinni Ko Ekun L'ona

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ, agbọ wipe awọn Lọya ti o ti gba oye Q.C. ni yio ṣe agbẹjọro fun Azikiwe ninu iwadi ọrọ, eyiti Ijọba Gẹsi yan alagba Sir Foster Sutton lati ṣe iwadi Continental Bank, bakanna ni awọn ẹgbẹ ti o mbọ wa ṣe ijẹri iwe owo gbogbo ti nwọn ti nkọ silẹ gba awọn Agbẹjọro meji ti o ti gba oye Q.C. lati ṣe aṣoju wọn ninu iwadi na.

Awọn ti yio joko ṣe iwadi na.

Awọn ti yio joko ṣe iwad ọrọ na niwọnyi:- Sir Foster Sutton adajọ agba ilẹ Nigeria. Maxime de-Comanmond, Adajọ agba ilu ilu Eko, Ọgbẹni V.A. Savage, adajọ Ila Orun, Eastern Region. ati Ọgbẹni Saunder ti yio ṣe olintoto gbogbo iwe owo ti nwọn ti nkọ silẹ

## Etutu igb'ade Oba.

ỌYỌ. Loni yi ni Alaiyeluwa Alafin Ladigbolu keji yio lọ ni agogo mẹjọ owurọ yi si Oko nibi Ojubọ Orisa Ọranyan, yio pa odidi ẹran agbo kan fi rubọ si, awon ijoye meji nwọnyi Agbakin, ati Osi-Ẹfa ni yio ṣe etutu nidi Ọranyan. Nigbati nwọn ba pari etutu tan, ni agogo kan, nwọn o pada bọ lati Oko.

Nigbati o ba di ọjọ Saturday ọsẹ to mbọ 25th oṣu Aug 1956. Alafin yio lọ si Gudugbu nibi ojubọ oriṣa Ogun, yio si tun ṣe etutu nibẹ. Bi nwọn ba pari etutu tan, Alafin yio pada si Ipadi, niwọn agogo kan ọsan. Ki ade pẹ lori, ki bata pẹ lẹsẹ.

Kabiyesi o.

## Oku olomo gege lao gbe

ABẸOKUTA. Anu ṣe ni lati jibin iku Iyafin Jọlade ni Agọodo. Ologbe na to ẹni ọgọrin ọdun nigbati o fi aiye silẹ. Enia pọ nibi oku iya na.

Orukọ awọn ọmọ Oloku ni Ọgbẹni Salami Salakọ ati Ọmọtẹni. Awọn ẹgbẹ Ọbanibaṣiri ninu eyiti Ọgbẹni S. Salakọ jẹ ọkan pataki ṣe gudu-gudu mefe.

Diẹ ninu awọn gbajumọ ẹgbẹ yi ti o nawo-nọra nibi oku yi ni awọn Ọgbẹni L. Bello, Y. Jọlaoṣo, ati S. Ṣofidiya, Kọta-Master, S. Barber ati Mako, Olori awọn Dọrẹba nibi iṣẹ G. B. Ollivant.

Ọba ko fi ori ji oku na, ki o si jẹki ẹhin iya na dara si owo, ki o dara si ọmọ.

## Ko nse gbogbo Larubawa lo faramo Egypt

DAMASKU. Baba ẹgbẹ orilẹ ede awọn Kọra kọwe ranṣẹ si Nassar nilẹ Egypt pe niwọn ni nkan mọ, iwọn iba diẹ ni ko fa ijọgbọn nipa ebute Suez mọ.

Eyiyi fi han wipe, ko nṣe gbogbo orilẹ Larubawa lo fi ara mọ ohun ti Nassar nṣe nilẹ Egypt. Awọn oṣiṣẹ ilẹ Larubawa ṣe ileri wipe. Bi ogun ba dide si Egypt, tabitabi ko si, awọn yio fi ẹtu fọ oju ọna ti epo mọto ngba lọ sinu Tanki.

Ọrọ ko dọgba lori ebute Suez yi kakiri agbaiye, ni gbati nwọn lọ sọrọ na nilu London laipẹ yi ni igbimọ.

## Egypt Fi Agbara Le Oyinbo Meji

Awọn alaṣẹ ilẹ Egypt fi tipa-tipa le awọn oyinbo meji ti o n'ṣowo epo mọto jade kuro nilu wọn lẹhin ti nwọn ti fun wọn ni iwe wipe, awọn fun awọn oyinbo elepo na ni aye fun wakati mẹrinlelogun (odidi ọjọ kan gbako) ṣugbọn awọn oyinbo elepo na ko tilẹ fẹ mọ pe ẹnikan sọrọ.

Nigbati wakati ti nwọn dafun wọn to, awọn ọlọpa yọ si awọn oyinbo mejeji na nwọn si fi mọto ko wọn lọ si ebute Said (Port Said) Ibẹ ni awọn alaiṣẹ ilẹ Egypt ti fi wọn nikọ wipe, ki a wa wọn pada lọ si ebute London.

Aṣoju Gẹsi ti o mbẹ n'ilu Egypt kọ e ibinu si awọn alaṣẹ ilu na fun iwa ti nwọn hu na. Aṣoju ijọba Egypt si fun lesi wipe, lile ti nwọn le wọn l'odara, bi nwọn ko ba ṣe bẹ, nkan miran iba ṣẹlẹ.


**Nje ise agbara ti o se l'oko ni? Fi egbogi yi pa ibiti o ndun o**



ELECTRIC
Balm





### IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ ewa ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

ỌMỌRELA BABY MIXTURE
*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)*
O wa Lọdọ :—
COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS


NO. 110.

## Factories Ordinance (No. 33 of 1955).

The Factories Ordinance comes into force on the 1st September 1956, and all owners or occupiers of premises which constitute a factory are hereby called upon to register any premises which come within the legal definition of "Factory".

Advice on this point can be obtained from the Department of Labour, Ikoyi Road, Lagos, or from the Labour Office in:—

| | | |
|---|---|---|
| Lagos. | Enugu. | Kaduna. |
| Ikeja. | Aba. | Jos. |
| Ibadan | Calabar. | Kano. |
| Benin. | Abakaliki. | Ilorin. |
| Warri. | Buea. | |

Forms for the purpose of applying for registration can also be obtained from these offices.

Attention is drawn to the provision in the Ordinance that it will be illegal to occupy a factory from 1st October 1956 onwards unless it has been registered in accordance with this notice.

By Order,
Commissioner of Labour.

# ELETI QFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJQ
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS

28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - QFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. VIII. NO. 481, LAGOS, SATURDAY AUG, 18. 1956.


## Agbalagba ki wa l'oja k'ori omo tuntun wo.

A ro si ẹtọ lati fi aṣiyan ọrọ wọ́ṣika wa ọsẹ yi ṣe alaye fun ẹnyin ọkawe wa lori rogbodiyan to bẹ silẹ niha Ila-Orun (Eastern Region) nipa owo ijọba ti nwọn lọ ko sinu Ile Ifowopamọsi ti a npe ni African Continental Bank ti ọlọla Dokita Azikiwe ti iṣe Alakoso (Prime Minster) Ijọba Ila - Orun, jẹ Alaga Ile Ifowopamọsi na.

### KILO FA SABABI?

Gbogbo yin ni ẹ o ti gbọ nipa imọran ti ọlọla ọgbẹni Eyo da ninu ile Igbimọ Aṣofin ilẹ Ibo wipe ki nwọn ṣe iwadi lori owo ijọba ti awọn igbimọ ko sinu Ile Ifowopamọsi na, ti ọrọ na fẹ da ruke rudo silẹ l'arin awọn ọlọla Oligbimọ ijọba Ila - Orun, eyiti Gomina wọn dasi ọrọ na nitoripe ki o ma ba si ikunsinu l'arin awọn igbimọ to mu ijanu ijọba dani ko ọrọ rẹ.

### AGBALAGBA KI WA L'OJA K'ORI QMO TUNTUN WO.

Owe Yoruba yi ni ọlọla Onikoyi-oko, (Secretary of State), tẹle ti o fi ṣe eto wipe ki a ṣe iwadi ọrọ na ki ara ọlọla Dokita Azikiwe le mo l'oju araiye nitoripe ọrọ a fi abuku kan ọlọla Dokita Azikiwe ati Ijọba Ila-Orun.

ETO IWADI

1. Ki a wadi gẹgẹbi iwa ti ko tọ suna ti nwọn sọ si Dokita Azikiwe lara nipa iṣẹ Ile-Ifowopamọsi ti a npe ni African Continental Bank.
2. Ki a wadi gẹgẹbi owo ijọba Ila-Orun ti ṣe de Ile-Ifowopamọsi na.
3. Ki a wadi bi Dokita Azikiwe ti jẹ polu Ile-Ifowopamọsi na, bi Alakoso tabi Alaga tabi o ni ipin pataki ninu ile Ifowopamọsi na, ki o to di Alakoso ijọba Ila-orun tabi lẹhin ti o ti di Alakoso ijọba Ila - Orun. Ati be bẹ lọ.

Ọrọ na yio di yiyẹwo ni ilu Eko ni nkan bi ọjọ kẹtadin-logbọn oṣu yi tabi ki nwọn tun sọ ọjọ gan ti iwadi na yio bẹrẹ.

A ṣe eyi nìba ṣoki fun anfani ẹnyin ọkawe wa, gẹgẹbi ati tẹ ikede ijọba l'ori ọrọ na si apakan Iwe Irohin wa yi ni ede Oyinbo ki o le ye yin daradara.

## Baba Isinku Farakorin

JOS. Irohin kan ti a gbọ lati ilu Jos ni wipe ọkunrin kan ti o ṣe Baba Isinku arakunrin rẹ fi ọgbọn eru yi owo girimọyan ti iṣe ti ẹniti o ku na si lilo ti ararẹ.

A gbọ wipe Kotu Jos da l'ẹbi ẹwọn ọdun mẹta abọ.

Ẹnyin Baba Isinku, ẹ fi eyi k'ọgbọn o.

**Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe**

No. 111.

## PUBLIC NOTICE

# Secretary Of State's Tribunal Of Inquiry.

It is announced for public information that the Tribunal of Inquiry established by the Secretary of State is expected to open in Lagos on or about the 27th of August: the exact date will be notified separately in due course. The terms of reference of the Tribunal are as follows:-

1. Allegations of improper conduct on the part of Dr. Nnamdi Azikiwe, Premier of the Eastern Region of Nigeria, in connection with the affairs of the African Continental Bank Limited.
2. The circumstances in which securities, or the proceeds of securities, belonging to the Eastern Regional Marketing Board, were transferred to the Eastern Region Finance Corporation and the circumstances in which such proceeds were invested in or deposited with the African Continental Bank Limited by the Eastern Region Finance Corporation.
3. The relationship, direct or indirect, between Dr. Nnamdi Azikiwe and the African Continental Bank Limited, its Directors, share-holders or officers, at all times, whether before or after such investment or deposit as aforesaid, material to the circumstances as aforesaid.
4. The relationship between the Eastern Region Finance Corporation and the African Continental Bank Limited at all material times as aforesaid.
5. The relationship between any body or organization, corporate or unincorporate, in which Dr. Nnamdi Azikiwe, has or had at any material time as aforesaid an interest, whether direct or indirect, and the African Continental Bank Limited.
6. The use made of the resources of the Continental Bank Limited whether before or after the investments and deposits referred to in paragraph 2 were made insofar as any such use appears to the Commission to be material for the foregoing purposes.
7. Whether in respect of any of the aforesaid matters any person holding Ministerial or other public office has infringed the standards of conduct demanded of the holder of such office and if so in what respect.

It is the desire of the Tribunal that all facts relevant to these matters should be put before them. Any member of the public who possesses information having a bearing on any of the Matters raised in the terms of reference is invited to submit a statement in writing to the Secretary to the Tribunal or to make an appointment to give an oral statement to an official of the Tribunal either in Lagos or Enugu.

The Supreme Court, Lagos.

K. J. Hilton
Secretary to the Tribunal


## ABOKI



JẸ AWOGBARUN to LOKIKI KA ILẸ ENIA DUDU.
AJẸBIDAN ni fun IKỌ, LAKUREGBE, IWORA, AKOKORO, SOBIA, AKANDUN, JẸDIJẸDI, etc.

KOṢEFẸKU ni GBOGBONṢE yi jẹ fun GBOGBO ILE nitorina RA IGO kan LONI Lọdọ-

**IBUKUN - OLU MEDICINE STORES,**

Amunigun Street, Box 245, Phone 189x, IBADAN

E 21, Sabongeri, ZARIA, X 5, Central Market, Box 2205, Kumasi, Gold Coast.

## Olopa kan lu omo odo re Sese

IBADAN. A gbọ irohin wipe, ọlọpa kan bẹrẹ si lu ọmọ ọdọ rẹ ni ilukulu tobẹ ti ẹjẹ fi nda jade ni imu ati ẹnu rẹ, tobẹgẹ, nwọn ni lati gbe lọ sile alaisan. Agbare - gbabọ, ọmọ na si ku lọjọ keji, bẹni ọrọ na ba di ijọgbọn si ọlọpa na lọrun.

Nigbati nwọn nṣe iwadi ohun ti o ṣe oniko iku to pa ọmọ na niwaju adajọ Ọgbẹni H. Ọbafẹmi nilu Ibadan, ibẹ ni Ọlọpa ẹlẹgbẹ rẹ ti o kọkọ wa jẹri ti sọ wipe, on ri nigbati o nlu ọmọde na, gbogbo akoko, ti o si fi lu ọmọ na fẹrẹ to wakati meji gbako.

Ọlọpa keji ti o tun jẹri nipa ọmọde sọ wipe, on ri I lasiko ti o nlu ọmọde na gbogbo ori rẹ lo kun fun ọgbẹ. On si bere lọwọ ọlọpa na wipe, kini ohun ti ọmọde na ṣẹ? O si dahun wipe, ko nlọ sile iwe ere lo nṣe kakiri nipa bayi ko yege ninu ẹkọ rẹ.

Dọkita to yẹ oku ọmọ na wo sọ wipe, ohun ti o ṣe iku pa ọmọ na, dabi eyiti o ṣubu lulẹ lati ori oke giga, ti ẹjẹ fi nṣan ni imu ati ẹnu rẹ jade. Adajọ sọ wipe, ọlọpa na yio de iwaju awọn alaṣẹ sọ ti ẹnu rẹ.

## Egypt wi tire jade

Nassar ti o nṣe Baba ẹgbẹ nilẹ Egypt sọ ti ẹnu rẹ jade o wipe, Ebute Suez, tiwa ni, ogun wa si ni pẹlu, a ko ji, bẹni a ko gba lọwọ ẹnikan; ẹtọ wa ni.

Ako tun fẹ wa labẹ ijọba kọkan, ijọba kan ni awajẹ ninu Ominira ni a si wa pẹlu ogun wa, ati ẹtọ wa ni a si nja fun.

Mo ti lero lati lọ ba wọn ṣe ipade ni London ti ṣugbọn ohun ti ko tan jẹ ko ri bẹ mọ, ni wipe, Ọgbẹni Anthony Eden sọ jade ni London wipe on ko ni gba ọrọ mi gbọ mọ.

Nigbati ọrọ si jẹ bayi, kini mo nlọ ṣe ni London.

Nassar sọ pe on dupẹ jọjọ lọwọ awọn orilẹ ede Larubawa fun ẹmi iṣọkan ati idide ti nwọn dide si ọrọ yi,

Mo fẹ ki ẹ mọ daju daradara ẹnyin ọmọ iya mi wipe mo ti duro bi HA! ninu ọrọ to delẹ yi

Nigbati Egypt ti gba ebute Suez pada yi, awọn ẹya Larubawa sọ wipe ebute Suez ko nṣe ti ara Egypt nikan bi koṣe ti iran gbogbo ẹya Larubawa,

Asi tun gbọ lati ilu London wipe bi awọn Egypt ba kọ ti nwọn ko ba wa si ipade, awọn ilu mejilelogun yio wa ninu mẹrinlelogun ti a pe, a o si ṣe ipade apero na.

## Kini eredi irokeke yi.

CYPRUS. Agbọ wipe ni ilu yi awọn ọmọ ọsọlẹ meji fi kareta si oju, nwọn fa ibọn yọ, nwọn wọ ṣọbu kan nibiti nwọn gbe nmu omi gbigbona (Tea) nwọn na ibọn si gbogbo awọn ti nwọn ba nibẹ, nwọn ni ki nwọn dide, ki nwọn kọju si ara ogiri.

Lẹhin ti nwọn mu ohun ti nwọn fẹ tan ninu ṣọbu na, ẹnikan ti ọlẹ ẹya Griki ti o mbọ larin wọn nikanṣoṣo ni nwọn pa.

Nwọn tun fi ẹtu Bomb kan si abẹ Mọto kan ti o duro, nireti pe Mọto na ba ti bẹrẹ si ṣiṣẹ, ẹtu na nilati gbina ki o si ṣe jamba fun ẹniti o wa ninu Mọto na.

Ṣugbọn ẹnikan koiti wọ Mọto na nigbati Bọmbu na gbina ẹnikan ko fi ara pa, Mọto na nikan lo bajẹ.



# Ejo Fashanu f'ori gbagi.

IBADAN—Ẹjọ ti Ọgbẹni Adewale Fashanu pe Gomina Iwọ-Orun ati Oloye Ọlọla Rotimi Williams nipa yiyan ti nwọn yan Oloye Williams si aye ipo rẹ ninu iṣẹ Ijọba Iwọ Orun pe ko tọ suna.

Adajọ Ọgbẹni J. I. C. Taylor sọ wipe aiko ṣe iwadi ọrọ na lọdọ Gomina to jẹ ẹniti aṣẹ iru ọrọ bẹ wa lọwọ rẹ, mu ki on fawe ẹjọ na ya. Ki Ọgbẹni Fashanu si san ọgọrin pọun, ọgọrin ṣile fun Gomina ati Oloye Williams fun owo irin ẹsẹ.

Abọ rẹ o.

## Fun Alafia Ara ati Agbara Ninu Eje



HOMMEL'S

# HÆMATOGEN

Lọ sọdọ awọn ti o nta ẹgbogi Hommel's Haematogen l'oni, ki o si ra igo kan. Ki o ma lo nigba gbogbo titi ti yio fi bẹrẹ si fun ọ ni agbara, nigbati yio ba fi to ọsẹ kan, awọn ọrẹ rẹ yio ri i, ati pe iwọ papa yio ri ayipada iyanu ninu alafia ara to njade ni oju rẹ.

FUN ỌMỌ TO NṢE AISAN TI O SI NRU

Onişegun Oyinbo sọ wipe egbogi Haemetogen dara fun iru ọmọ bẹ. O nfi ẹjẹ titun siwọn lara, laipẹ alafia ati agbara yio de si ọmọ na.

Ohun pataki ni egbogi yi jẹ fun awọn o i.



mbẹ ninu igo fun tita ni Sobu egbogi kakiri ile Nigeria. Bere lodo Asoju wa:-

2, ALBAN PHARMACY LIMITED
Victoria Street. P. O. Box 461
LAGOS — NIGERIA.

# Eniti O Ba Pa Enia, Ye Ki A Pa On na

Nipa ibẹrẹ ọrọ oke yi ti o jade ninu iwe irohin wa, Ọlọrun Ọba lo sọrọ nwọnyi pe "Iwọ ko gbọdọ pa enia" ati "Ẹnikẹni ti o ba pa enia, lori rẹ lao ti mu ida koja". Ofin yi lati ọdọ Ọlorun wa ni.

Bi a ba lọ ṣe ofin wipe ki a maşe pa awọn apania mọ, nṣe ni ọrun yio ma gba alejo, ti ọgba ẹwọn yio si kun ṣọṣọ. Nigbana ile aiye ko ni dun lati gbe, bẹni ọrun ko ni ṣe re. Aiye yio tun padà sigba kutukutu owurọ, nigbati ipania wọpọ.

Nitori iru iwa bayi ni a ṣe npe ijọba Gẹsi ni Olododo, bẹni ododo lo ngbe orilẹ ede leke. Şugbọn bi nwọn ba yi ofin pada, ti nwọn si ngbe ẹjọ alare fun ẹlẹbi, kini nwọn fi san ju Faranse ati Jamani lọ. Ki ẹ si fi oju inu wo o, kini ere aişododo, fa wa ba awọn ilu mejeji na lori, ko si alafia, bẹni ko si ifọkanbalẹ. Bi enia ba nyọ'lẹ da, ohun wẹrọ-wẹrọ a si ma yọ wọn ṣe.

Iye awọn to fi ara mọ imọran temi yi ni Ọgbẹni Y.A. Agbaje, ara Kumasi ati Ọgbẹni J.A. Afọlayan ara Ebute metta.

Olotu

# Alapinni ati Agbakin lo fori bale f'oba

ỌYỌ. Oloye Alapinni ati Agbakin ti awọn mejeji jẹ ara awọn Ọyọmisi ati ara awọn ọmọ ẹgbẹ Ọyo Parapọ-N.C.N.C. lọ ba Oloye Başọrun nile, wipe ki o fi oriji wọn.

Başọrun gba o si fi'ori ji wọn. Nwọn wa so fun Başọrun pe bawo ni yio ṣe mu awọn yọju si ọba, ki awọn le lọ ṣe etutu ti o ba kan wọn fun ọba.

Nwọn si şelori wipe gbogbo edekoyede ti o ti mbẹ larin wọn si ọba, ti wọle, ti ọba ni awọn o si ma şe.

Başọrun ti ko wọn sodi lọ kerufu ati lati tuba fun ọba "Ẹyẹ ni ọba nfi ori bibẹ ṣe ọba ko nmu ẹjẹ"". (owe Yoruba).

Loni ni Oko, nile Ogun, Alapinni na ati Agbakin ni yio şe tutu lojubọ Ọranyan.

# Enyin Agbe, Eti Nyin Melo ?

Awọn Yoruba lo np'owe wipe ogun agbọ-tẹlẹ ko np'arọ. Irohin ti a gbọ ni lọwọ-lọwọ yi ni wipe awọn Eşu nsunmọ eti'le.

Awọn eşu ti o fọlọ si apa ilẹ Tunisia ti bẹrẹ si pamọ, a si tun gbọ pe ọpọ awọn ti o folọ silẹ Maroko ati ilẹ Algeria ti pamọ ogidi nleje wọn lo pamọ si eti odo Şadi (Chad).

Nitorina awọn ti o pamọ silẹ Moroko, Algeria, ati agbegbe ilẹ Faranse, bi awọn ọmọ wọn ba gunyẹ apa ọna ilẹ Hausa ni nwọn mbọ. awọn ti o si fo lọ si apa ilẹ Sudan pẹlu le fo wa si ilẹ Nigeria.

Ẹnyin agbẹ ẹ maşe ja fara lati ba awọn eşu na sọrọ gẹgẹbi ti ọdun 1930, nitori nwọn ni eti lati fi gbọ ọrọ.

## Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe

## Now Available

BUGLES, BEDSTEADS, PAINTS, DISTEMPERS SAFES Etc.
Just Write, Call Or Phone 21372
IKORODU TRADING COMPANY
30/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS.
and NEW COURT ROAD, IBADAN.

## Kere o!

A ti ni orişirişi ogun Germany to şeşẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS
MEDICINE STORES
7. Egerton Road, Lagos

## Omo [illegible] Po L'aiye

NEW YORK. Awon ojogbon ile Amerika ti o nwoye [illegible] nkan ti nlo [illegible] se akiyesi bi enia ti nwo sile aye to, awon [illegible] enia ti nwo ile aiye ra. Lodun 1955 [illegible] enia ti o mbe lori'le aiye je 2,692,000,000.
AFRIKA. Gbogbo enia ti o mbe ni erekusu ile Afrika tele-tele ti je 224,000,000. sugbon nisisiyi 1955, o ti le [illegible] 40,000,000 enia.
ASIA je 1,481,000,000, sugbon 30 million ni esi.
EUROPE. 411 million o le 7,000,000 l'esi.
AMERIKA 362 million o le 5 million. Awon to ngbe arin meji agbami okun rere je 14.6 million o le 2 million.

Sugbon ni agbegbe ile Rosia nikan iye awon enia to mbe nibe je 200.2 million
Awon ara ile China je 582.6 million. Awon ara ile India 332 million. Awon ara U.S.A. je 164.2 Ayani, ori i, ile aiye nkun beni onun ko se re wara-wara.

## Eyiyi yio ha se se bi?

Irohin kan wa wipe ni Asale Oko kan ti ko si igi ti o hu jade nibe ko si igbo, ko si omi, ko si koriko, ko si Laba-laba, ko si Esin-esin, ko si kokero.

Asale Oko yi ni awon Rosia gbero lati so di ile eleta loju,ti nwon si ma fi ile ibe da Oko fun owu'

Nwon o la ona fun omi odo lati san wo inu re.

Nitoripe nwon nfe owu bi iwon 340.000 l'ododun, ero won ni lati so ibe di Oko oba.





## ORIKI BAMWO

Bamwo de, alajela omode agbomola bi orisa, akokoluko ogun ti nda'mo l'ekun igbona, atata ogun ti np'o tutu re warawara a je bi idan, a gba bi etu ibon. O s'abiku di ikugbagbe, o s'omo ti nbehin l'ore. Iko ri i sa, Iba ko l'ona tagiri, aiperi ri d'ekun iyonu Olugbala f'omo ti nyagbe orin o kapa inu wo, o lu jedi l'alupa, gbogbo abiyamo nyo sese. Ela ri i o roju, Orese ri i o na'gbe bo'ra. Eyi npa'lemo lodileso, ore ikoko, kosemani awon abiyamo, eni araiye njijadu ra. O de'lu Ibo, o dega, o de'le Hausa, o d'oba, gbogbo Onisegun l'o ro pe ko legbe, gbogbo omode lo nfe e fun ilera.

*IGO KEKERE 2/6d IGO NLA 4/6d*
owo oko 1/6d fun igo kan.

THE EGBA TRADING
ARADAN STORES

18, Denton Bridge, Street,
P.O. Box 2, Ebute-Meta.


Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe


UNDERSTANDING THE BIBLE

For free book making clear the teaching of the Bible, write to: Bible Mission, (Room 16) 2, Grays Road, Slough, England.




OLOYE E.A FADAIRO
Okan ninu awon Asofin Ijoba Igbimo Iwo-Orun, ninu Ibadan.

Aworan inu iwe wa yi niti Oloye Olola E.A. Fadairo ti ise okan pataki ninu awon Olugbimo Asofin Iwo Orun.

Ogbeni Fadairo lo j'abo ise re fun awon ti o yan sinu ile igbimo na ninu Ipade Ajo igbimo ibile ti ilu Ilaro.

Gbogbo igbimo na lo da muso fun u. Eyi wu wa o, Oloye ti wa.





Ibikibi ti ani oloiki KINIUM-FILLIPI ba wa o je ilowotoya fun AGBARA alailegbe ati ewa ti a fi se ise.

Awon irin-are Basikulu FILLIPI (frames and forks) ni awon akanse ise ti a se sinu won biotilejepe ko han sode nwon fi agbara aiope si ibiti ye. Iwadi iseona to le ni ogbta-odun lo fun wa ni igboiya lati wipe KINIUM-FILLIPI ai yio ma gbori lowo gbogbo won.




PHILLIPS CYCLES LIMITED, BIRMINGHAM, ENGLAND

ORUKO —

ADIRESI ILE —


Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 28 Koroko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23174